# OLOGBE ẸNI-ỌWỌ BISHOPU

## I. OLUWỌLE, D.D.

A bi Ẹni-ọwọ Bişọpu Isaac Oluwọle ni oşu June ni ọdun 1852, o ku li àgba ni Ọjọ kẹtalelogun oşu July ni ọdun 1932. Fun iwọn ọdun meji ki titan to de ni ailera ti sé e mọ́ ile li Eko ti kò si le lọ kākiri mọ lati şe işẹ rẹ̀ bi Bişọpu, şugbọn ni ìgba meji ni o sapá lati şe Isin Ifini soye Alufa ni (Şọşi) Katidrali li Eko. Nigbati o kù diẹ ki ọdun èşi pari, o lọ si Abẹokutā ati Ibadan fun ati şe akoso awọn Ipade Igbimọ Ẹkùn ibẹ ati lati şe Isin Konfirmation. Ni akoko aile ara rẹ̀ yi pẹlu li o lọ si Abẹokuta lati lọ wāsu nigbati a şe Isin Iranti Ọgọrun-ọdun ti a ti tẹ ilu nā do; a ô si ranti bi ailera nā ti fẹrẹ mu ki o şubu lati ori igi iwāsu nigbati o nwāsu lọwọ, iwāsu ti a ko le gbagbe titi. Nigbati o pada bọ̀ si Eko, ilera kò si fun mọ́, nigbati o si di oşu March ti o koja, o kọ iwe si Bişọpu Eko pe on fẹ lati fi işẹ on bi Oluranlọwọ Bişọpu silẹ ni ọjọ nimọ ti Aposteli Peter—Ọjọ kọkandilọgbọn oşu June, ti isi şe ájọdun kọkandilogoji ti a fi jẹ oye Bişọpu.

Ni ipade Igbimọ Diosisi (Diocesan Board) ni Bişọpu Melville Jones kọ́ sọ pe Bişọpu Oluwọle fi işẹ silẹ şāju ki o to tun sọ ọ ni Ipade Sinọdi ni oşu May ti o kọjá, nigbati a si kọ ọ silẹ fun iranti bi gbogbo awọn èro Ipade na ti ba a kẹdùn to fun ailera rẹ̀, ati bi fifi işẹ silẹ rẹ́ ti jẹ ẹ̀dun ọkan wọn.